**Wanted**

Two Young Reporter who can Manage a Yoruba News paper and collect Advertisements

Apply in persons:-
To
IROHIN IMOLE
16 Bamgbose St.
Lagos.

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

Two Journeyman Printers and one Advance Printer

Apply in persons:
To
Modupe Printing Press.
16 Bamgbose ST.
Lagos.

VOL. V No. 208 MONDAY MAY 29 — JUNE 4 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Omi Okun ya lu awon ara Okun Apese ati awon ara Okun Alasia

EKO:- NI AKOKO TI AWỌN ARA ILU EKO NYỌ AYỌ ATI IDUN-NU TI ỌDUN ILEYA TI NWỌN NJẸ ẸRAN TI NWỌN NJẸ AGBO NI A GBỌ IROHIN PE OMI OKUN TI BINU YA LU AWỌN ARA ABULE APẸSẸ, ATI AWỌN OKUN ALASIA TO BẸ TI INU ILE KOṢE SA SI FUN ABO.

Ko si awọn ara eti okun ti nwọn le wọ inu ile wọn sun nitoripe, Omi okun mu awọn ẹlomiran de Itan ninu yara wọn nṣe ni busun wọn wa lori efo lori rẹ ni nwọn si ko gbogbo ẹru inu ile le lori.

Eyi nikan kọ, awọn ara Abule mejeji wọnyi ko ri omi mu, ninu rẹ ni omi okun ti yabo molẹ.

Titi di bi a ti nwi yi, ko si enifi o le gboju-gboya lati gbe ọkọ si oju omi pe on lọ pa ẹja Owe awọn Baba wa kan sọ bayi wipe, Okun le Aganyin ko wẹ, A tilẹ gbọ wipe lati ọjọ ọdun na ojojumọ ni okun nru goke.

Awọn Aladura Serafu ti nwọn pagọ kakiri eti Okun ni a gbọ wipe Okun n. fi wọn ṣe awaro ri ti omi Epiya ọkunriu ijoye kan larin nwọn Aganyin ara ilẹ Ghana ti ngbe eti Okun nibẹ Oa lọ sọ wipe iru nkan bayi ko le ṣe ko ma ṣẹlẹ larin ọdun kan ṣugbọn irufẹ nkan bayi ti ṣẹlẹ o le lọdun mẹwa sẹhin.

## Eko Olofe pataki mbe fun Omo Eko



Eko:- Alayeluwa ọba Adele keji sọ ni Moṣalasi ọdun ti Eko wipe, iwa buruku pọju nilu yi, bi iru iwa ti ko ti lẹ yẹ lati ma gbọ ki awọn Angẹli le fi ojure woni. Bi a ba ti ri ẹnikan ti o nhuwa bi alaibikita fun ofin iru iwọnyi, ni awọn ọmọ Eko yio ma ka si ohun gunmọ, ti nwọn o si ma kan sara si oluwa rẹ.

Ko si ẹni ti o le tẹ aiye lọrun, bi koṣe wipe awọn enia gba Ọlọrun gbọ, nwọn si bọwọ fun U. Bi o ba jẹ ọrọ nipa Ẹkọ nko jẹ danu duro, si sọ na ni a o ma sọ ọ, titi awọn iran ti o mbọ yio fi ri daju wipe nigba aiye ọba Adele, a ṣe iwọn iba ti a lẹ ṣe gẹgẹ bi ọba ilu Eko, aya fi bi a ba fun awọn ọmọ ilẹ wa ni ẹkọ ti o ye koro, ni ipo nwọn yio fi dara lẹhin ọla.

Mo sọ fun nyin pe, awọn ọmọ ko ni ẹkọ ti o ye koro to nigbati mo ba nyin sọrọ ni hin gbẹ hin, ọrọ na fẹrẹ dabi asọjuṣugbọn ẹniti o ba ni ifẹ ilu rẹ lọ kan, yio ma funrere nipa ẹkọ awọn ọmọ wa.

Gbogbo awọn Ijọba ilẹ Naijiria lo nran omo awọn lọ fun ilosiwaju ẹkọ kakiri aiye, ṣugbọn mo gboiya lati sọ fun nyin wipe Ijọba Alapapọṣe ti se tan lati ran awọn ọmọ ibilẹ Eko ati awọn ti o ngbe ilu Eko ni Ẹkọ Ọlọfẹ orisi mẹta bayi:-

(a) Ijọba nfẹ ọmọ Eko ti ori rẹ peye fun ẹkọ isiro, ati fun ọgbọn ori (Mathematics & Science)

(b) Ijọba nfẹ ọmọ Eko ti yio lọ kọ iṣẹ Yọh-n-yọhin ati Isegun Oyinbo (Dentistry and Medicine)

(d) Ijọba tun nfẹ awọn ọmọ Eko ti yio lọ kọ iṣẹ nwọnyi, Iṣiro owo, Itọju awọn iwe, Iṣẹ Apogun, Iṣẹ Akọwe, Iṣẹ Olukọ ati Iṣẹ ọna.

# ISE KI 'PANI, AYO NI PA 'NIA.

O BẸRẸ LATI ỌṢẸ TO KỌJA

Nigbati ati da wọn si ile aiye, wọn ti ro pe awọn ni awọn ni ara nwọn, wọn gbagbe Ẹlẹda wọn, wọn si ti na mo ọna Esu. Idi rẹ ni-yi ti Ọlọrun fi sọ fun mi pe ki nmu wọn wa ki wọn si ma jiya titi ti ọjọ ajinde yio fi de." Nigbati wọn kiri inu ile yi t a n iku ni ki ọkunrin yi joko ki osi ṣọ ohun ti obe wa fun on. Ọkunrin yi si fẹ dọbalẹ niwaju rẹ ki oma sọ ọrọ ṣugbọn iku ni ki omase bẹ rara. 'Lẹhin eyi ni ọkunrin yi bẹrẹ si ọrọ isọ fun iku oni, "Mo wa ni ile

**Lati Owo:- Simeon Adegoke Faloki**

aiye lati igba ewe mi, mo si ṣe ọpọlọpọ wahala lati ri pe emi na ni lari laiye, ki nle jẹ ọ'ọ̀la, olowo ati ọlọgbọn enia, ṣugbọn bi m o se ti nse to yi k o ni iyọri rere kan. Ko si owo fun mi lati na, ko si aṣọ fun mi lati wọ, nkosi ri ile gbe. Bẹni ko si onjẹ fun mi lati jẹ sugbọn nigbati odi ọjọ kan mo wa r o n u pe oyeki nwa tọ iku lọ ki osi kuku mu mi kuro ni ode aiye ki asi jọ ma jẹ igbadun ni ọrun. Idi rẹ niyi ti mo fi de ibiyi."

Nigbati iku gbọ bayi oya ẹnu rẹ osi nsọrọ, bi oti nsọrọ ni ẹfin bẹrẹ si jade ni ẹnu, rẹ ti osi sọ bayi pe emi ki ba enia pa rara, ki nto pa enia emi gbọdọ kọkọ ri iṣẹ lati ọdọ Ayọ pe kị npa lagbaja, nitorina iwọ ọmọ enia mo fẹ ki o wa lọsi ọdọ Ayọ ki osi lọ gba iwe wa lẹhin na ni emi yio to lanfani lati pa ọ." Ẹnu ya ọkunrin yi pupọ nigbati ogbọ bayi nitoripe iku ara ma sọ pe noda enia ni ile aiye. Bi eleyi ku a ọ w i p e iku lo pa. Nigba ti ọkunrin yi ro ọrọ yi ti ko mọ eyi ti on yio se ni ọba bẹ iku ki o jọwọ ki o fi ọna ile Ayọ han on, ki o si lọ gba iwe wa si ọdọ i k u pe ki o pa on. Iku dide ni tọtọ osi fi ọna ile a y ọ han ọkunrin yi. Laifa ọrọ yi gun uọnkunrin yi t u n bẹrẹ irin rẹ onlọ. Orin titi ko ri ile kan ni adugbo ibi ti a juwe fun, sugbọn ni ọjọ kan ni o dede ba oku awẹn Arẹwa Obinrin ati Ọkunrin kan nilẹ ti asi kọ ako le kan si ẹgbẹ ọdọ wọn bayi pe, "A w ọ n ọkunrin ati obinrin arẹwa yi ti jẹ Ọlọla ni ile aiye ri wọn ti rijẹ, wọn ti ri mu, wọn ti kọ ile, ṣugbọn bi wọn ti ni gbogbo nkan ni ẹnu tẹrun bayi, wọn ko fi mo ebi wọn, wọn ko si mọ iran wọn, ọrẹ wọn Ọmọraiye. bẹni wọn ko si fi mọ Ọlọrun Ọba.

IYOKU DI ỌSẸ TO NBỌ


## KERE O, Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Ẹ ku afojuba E g b o g i pataki ti aṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Oniṣegun (Specialists.) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ Arun wọnyi:—

IGBONA:- Eyi yi jẹ Arun ti o ṣọpọ ni ode isisinyin papa ni arin awọn Omọde ati Agbalagba.
ORIFIFO TULU. LUKULUKU. OTUTU IGBA AYA. ARA RIRO, ati OTUTU ỌRẸREN pẹlu AKOKORO Jọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko to Afojuba

Bereiwo ti ẹ o fi lo lọwọ ọniti o ba ta E g b o g i na fun yin. Odeju hanwun, Ẹ o ri iṣẹ rẹ lẹhin iṣẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ awọn oniṣegun adugbo rẹ.

*Distributors*
HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23745

LAGOS


# IWE SI OLOTU

ẸKU ETỌ ATI ETO ILU, ENYIN AGBAGBA ATI AWỌN OLOYE ILU IPOKIA

Lati Ọwọ:- OMIDAN OYINLADUN

Olotu Iwe Irohin Imolẹ, ẹ jọwọ gba mi laye diẹ lati ki awọn agbagba ilu Ipokia ati awọn Oloye ati awọn Afọbajẹ pe nwọn ku eto nipa ki aiye mabajẹ, mo tun ki nyin pupọ pe, bi ẹ ti ṣe nlepa ilọsiwaju fun ilu Ipokia, gẹgẹ bi awọn ẹlomiran na ti ṣe nlepa ilọsiwaju ilu nwọn, Ọlọrun Olodunmare ki o jẹ ki o dara fun gbogbo wa o Amin.

Ọrọ pataki ti o mu mi ki nyin bayi nipe, a ko gbọ kuku, bẹni a ko si gbọ gbingbin, tabi Alagbẹdẹ ko saro ni, nipa aye Oye nlanla (Oye Aro Ipokia) ti aye rẹ ti si silẹ lati igbakan wa, ti ẹ ko si jẹ O y e na lati igbayi wa, mo mọ d a j u wipe ki nṣe wipe Ọmọ aye lo wọn ṣugbọn mo ro pe edekoyede ni ko lẹ jẹ ki o ri bẹ, nitori na mo bẹ nyin pe ki ẹ mase sun te ọrọ Oye na mọlẹ.

Ṣugbọn emi yio la nyin lo ye ohun pataki mẹta, to ṣe pataki ninu eto Oye. Ekini nipe:- Eni ti o ba nfẹ jẹ Oye Baba rẹ, oyẹ pe ki o jẹ ọmọ Oye ni idile Ọlọkunrin, ti ki iṣe pe Iya rẹ lọ bi si ibomiran, iyen ti di Ọmọlobirrin ni idile Oye na ni yẹn. Ekeji ni pe:- Eni ti a ri wipe Oye yi tọ si, iru ẹni bẹ, o yẹ ki o mọ iwe daju, ti o le kọ ti o si le ka, ṣugbọn ẹlomiran le mọ iwe ki o ye, ki o mo tọ si. Eketa ni pe:- Ọ b a ati awọn Oloye ati awọn Oṣelu ati awọn afọbajẹ yẹ lati wo iwa ti ẹni ti a nfẹ fi j o y e yi ni si ilu rẹ (Popularity or Career)

GBOGBO AWỌN O F I N WONYI NI IJOBA TI SE ETO RẸ F O L O Y E. TI NWỌN SI TI FỌWO SI

At wipe Egbe kẹ gbẹ ko di ni lọwọ Oye ile ẹni. A si ki Oloye Ọgbẹni Osa wipe o ku eto ilu, bẹni a si tun ki gbogbo awọn Ijoye ni ọkọkan p ẹ l u ati awọn Afọbajẹ ati Alaiye luwa Ọba wa Adeyanju Asinmate keji pe, o ku ẹtọ ati eto ilu, adura wa ni wipe Ilu naga toro le nyin lori o Amin.

## Omo ile Rhodesia kan ti o lo kose Oluko nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo nion aworan yi, ni Ọgbẹni kan ti o jọ Martin Chabateni ara ilẹ oke ni ipinlẹ Rhodesia, ti o fi ilu rẹ silẹ ti o lọ kọṣẹ Olukọ ni ibikan ti nwọn npe ni Oversea Visual Aids centre ni igboro ilu London.

Obinrin ti a nwo ti o bẹrẹ si ọdọ rẹ lo nfihan gẹgẹbi ti ṣe le ya aworan lati fi ṣe apejuwe bi nkan ti ri. Orukọ obinrin na njẹ Omidan M. Clarke.

## LAGOS EXECUTIVE DEVELOPMENT BOARD

### ORO TI ALAGA SO NIPA IWADI TI NWON SE LAIPE YI LORI ESUN TI NWON FI SUN AKOWE IGBIMO NA.

Igbimo yi ti se iwadi nipa orisirisi esun ti nwon fi sun akowe igbimo yi lati ile Igbimo nla, gegebi a ti ko si oju ewe 34, ati 35 ninu iwe kan ti a npe ni 'Hansard' Report ti ojo 20 osu April 1961. Lehin ti a ti ye iwe na wo daradara, iwonyi ni ipinnu wa.

(I) Igbimo wa yi gba wipe, ile ti a pin lati fi kole No. 451, ko nse ti ogbeni Olatunji Ajose Adeogun bi kose ti egbon re ti o nje Olayinka Ajose Ade-Ogun to fi mbere fun ile lati kole si lati odun 1951 nigbati nwon koiti gba Olatunji Ajose Adeogun si ise Akowe Igbimo yi.

(II) Iwe ase ile kiko No. 9015 ati 9114 ko nse eyiti Igbimo yi se fun Olatunji Ajose Adeogun bi kose ti egbon re ti o ni ile No 451.

(III) Ati wipe ileti o mbe ni No. 17, Rhodes Crescent je ti Iyafin Ajose Adeogun eyiti a fi le lowo ni odun 1957, lati owo Ogbeni kan ti nwon pe ni A. R. Amusa siwaju ki Olatunji Ajose to wo ise L. E. D. B.

(IV) Ile lati ko ile si No. 457 ti o wa ni Apapa ko nse ti O. A. Adeogun bi kose ti okunrin kan ti won npe ni Freeman la i odun 1954.

(V) Sugbon ile No. 610t/611 ti o mbe ni Apapa ni ile kansoso ti igbimo yi pin fun Ogbeni Olatunji Ajose Adeogun lona eto ati eye.

(VI) Iwe ase ile kiko No. 13766 je ti ile No. 610/611 lati ko ile sori ile na.

VII) Ile No. 610/611 ti a wi na, pe o je ti Olatunji Adeogun ni Ogbeni Olatunji Ajose Adeogun na ti pin die lara ile na fun awon Oyinbo Onikongirato (Contractor) Dys Trocca Valesia & CO.

(VIII) Ile meji nwonyi Nos. 391 ati 392 eyiti Igbimo yi pin lati fi ko ile kansoso papo si oju ... Itire, je eyiti a ta fun Iyafin O. Ajose Adeogun ni owo lowo, nigbati Munisipa polowo re fun tita nwon si sanwo re fun Town Council.

(IX) Sugbon a ko daruko eyiyi sinu iwe ti Igbimo nla (Representatives) fi se alaisun, Igbimo L. E. D. B sakiyesi pe ile No. 2543 ti o mbe ni Apapa je eyi a pin fun Ogbeni Olatunji Ajose ...gun, ni odun 1957, o si ti gbe ile na fun Ogbeni L. J. Dosunmu.

(X) Igbimo nla (Representatives) kosi ro eyi kun iwe esun won, sugbon Igbimo L. E. D. B. tun ri pe ile No. 285 ati 286 ni a pin fun Iyafin Ajose Adeogun lona ti o to wipe ki o fi ko Sobu si.

(XI) Ile ti o mbe ni gbalasa ita Massey (Massey Sqr) No. 6, ko nse ti Olatunji Ajose Adeogun, nigbati ta to piepin re de ibi ti nwon ti ngbawe ile, a ri wipe Olayinka A. Adeogun lo fi ile na haya fun Ogbeni B. A. Doherty.

(XII) Ju gbogbo re lo oro ti ko kan Olatunji A. Adeogun ni awon ile No. 451 ati ... ti o wa ni Apapa, a ko iti pin fun Ol... A. Adeogun Ile ti o wa ni (6 Massey Sqr) ko nse eyiti o lo suna nitori Ogbeni Adeogun ko ri ere kan je latari re, oro eleyi ko si kan Igbimo rara.

XIII) Nipa awon oro ti a ti nso bowa:-

Ile Nos. 601/611 ile kekere kan ti o wa nibe, lona

(a) Apapa, Olatunji Ajose Adeogun ni a pin fun lodun 1957 ki nwon to tun gbe fun Oyinbo Dys Trocca & Valesia ninu odun 1961.

(b) Ile No. 2543 ni biti enia ko po on ni a pin fun Olatunji A. Adeogun ni odun 1956 ... si ta a gbe fun Ogbeni L. J. Dosunmu ni odun 1958.

(c) Ile No. 285, ati 286 lati fi ko Sobu ... Apapa eniti a pin fun ni Iyafin Ajose Adergun

(d) Ile Nos. 391 ati 392 fun ile gbigbe kan ... a Itire Iyawo Ogbeni O. Ajose Adeogun lo ra nigbati won polowo re fun tita

(e) Gbogbo iwonyi ni a pin lona eto gegebi ase Igbimo.

(XIV) Gegebi ase ilana ti Igbimo ma nse, Igbimo yi ko nfun Oko-laya ni ile otooto ayafi ki o je toko taya

**Ilola KOFO ABAYOMI**
P. C., M. D., L. L. D., D. O. M. S., F. R. S. A.,

---

# IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi se ikede fun gbogbo Okawe Irohin Imole Jake-Jado Agbaiye ati awon Omo Karo-o-jire pe anfe:- Eniti o ba le ba wa fi awon oro si ibiti a fa ila kekere si, ati pe awon kan tun wa ninu re ti a ko to dadaanfe eniti o ba le ba wa to si ipo re daradara ti yio si ni itumo.

Enikeni ti o ba si bori ninu gbogbo re yio gba Ebun ponun-kan sile-kan (£1 : 1/-).

ORO NA NI WONYI

Oro yi je oruko awon enia pataki nile Yoruba ti nwon si ti di ologbe:-

1. _ _ A _ Y _ _.     6. M _ _ E _ _.
2. O _ _ N _ _.     7. _ A _ _ O.
3. _ _ U _ _ W _.     8. O _ O _ ... _ I·
4. O _ _ P _ _ _. 9. O _ _ N—O _ _.
5. B _ _ ... ... _ N.     10. A ... ... T _ _ _

Oruko yi je. oruko awon Oba nile Yoruba

1. O _ _ N _ _
2. E ... _ J _ _ B ...
3. A _ _ W _
4. O _ _ D _
5. A _ _ _ _ U _ _

Tun awon oro wonyi to dara-dara:-

1. GOOINANS _ _ _ _ _ _ _ _
2. AIJNIDE _ _ _ _ _ _ _
3. GABRNOI _ _ _ _ _ _ _
4. ASLIHE _ _ _ _ _ _
5. OINMMION _ _ _ _ _ _ _ _

Awon oruko wonyi je oruko Ilu ni ile Naijiria:

1. _ G _ O _ ... _
2. I _ B _ _ A ... O
3. K _ _ A ... C _ N
4. A _ ... T ... G _ O
5. ... A _ ... B _ R.

AKIYESI:— IDIJE yi yio pari ni gbigba ni ojo keta osu keje odun yi (3 : 7 : 61) ko oro tire ki o han rekete, eniti tire ko ba han, a o fa ya ni, ki e si mo daju wipe, ko si ojoro ninu Idije na, eniti o ba se gbogbo re, ti o si gba a, ni a o fun ni Ebun ponun-kan Sile-kan (£1 : 1/-) Postal order ranse si.

Fi Stamp Toro ranse fun gb'gbe ponun-kan Sile kan ti o ba jo ranse si o. Ge ibiti Idije yi gbe wa, ki o si fi ranse pelu Stamp Toro tire. Enikeni ti ko ba ge Idije tire ranse, ti ko ba si fi Stamp Toro ranse pelu, ti o ba je a ko ni fi ranse si onitohun, a ko si ni fun ni Stamp re pada mo

Oruko ____________________

Ibugbe ____________________

____________________

Ise ____________________

Ojo Ori ____________________

Fi Idije tire ranse si:—

**OLOTU IROHIN IMOLE**
16 BAMGBOSE STREET LAGOS